## *(92) Suratul - Laeli*

## سُورَةُ اللَّيْلِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye,*
*Aṣakẹ ọrun.*

بِسْمِ اللَّهِ الرَّحْمَٰنِ الرَّحِيمِ

**1.** Mo fi oru (Laelu) bura nigbati o ba bolẹ̀.

وَٱلَّيۡلِ إِذَا يَغۡشَىٰ ١

**2.** Ati ọsan nigbati o mọlẹ yàn.

وَٱلنَّهَارِ إِذَا تَجَلَّىٰ ٢

**3.** Ati dida akọ ati abo.

وَمَا خَلَقَ ٱلذَّكَرَ وَٱلۡأُنثَىٰٓ ٣

**4.** Dajudaju ọna iṣẹ nyin, ọtõtọ̀ ni.

إِنَّ سَعۡيَكُمۡ لَشَتَّىٰ ٤

**5.** Ki ẹ ri ẹniti o ntọrẹ ti o si npaiya (Ọlọhun).

فَأَمَّا مَنۡ أَعۡطَىٰ وَٱتَّقَىٰ ٥

**6.** Ti o gba ohun rere si ododo.

وَصَدَّقَ بِٱلۡحُسۡنَىٰ ٦

**7.** Nitorina A o fi on ṣe kongẹ irọrun na.

فَسَنُيَسِّرُهُۥ لِلۡيُسۡرَىٰ ٧

**8.** Ki ẹ ri ẹniti o ṣe ahun ti o ro pe on to tan.

وَأَمَّا مَنۢ بَخِلَ وَٱسۡتَغۡنَىٰ ٨

**9.** Ti o si pe ohun ti o dara nirọ.

وَكَذَّبَ بِٱلۡحُسۡنَىٰ ٩

**10.** Nitorina A o fi on ṣe kongẹ inira na.

فَسَنُيَسِّرُهُۥ لِلۡعُسۡرَىٰ ١٠

**11.** Dukia rẹ̀ kò ni ṣe e ni õre kan nigbati o ba parun.

وَمَا يُغۡنِي عَنۡهُ مَالُهُۥٓ إِذَا تَرَدَّىٰٓ ١١

**12.** Dajudaju ti Wa ni itọnisọna.

إِنَّ عَلَيۡنَا لَلۡهُدَىٰ ١٢

**13.** Atipe dajudaju ti Wa ni ọ̀run ati aiye.

وَإِنَّ لَنَا لَلۡأٓخِرَةَ وَٱلۡأُولَىٰ ١٣

**14.** Nitorina Emi fi ina ti o njo fofo ṣe kilọkilọ fun nyin.

فَأَنذَرۡتُكُمۡ نَارٗا تَلَظَّىٰ ١٤

**15.** Ti ẹnikan kò ni wọ̀ ọ ju olori buruku lọ.

لَا يَصْلَىٰهَآ إِلَّا ٱلْأَشْقَى ١٥

**16.** Ẹniti o npe (otitọ) nirọ ti o ṣẹri.

ٱلَّذِى كَذَّبَ وَتَوَلَّىٰ ١٦

**17.** Atipe awọn olupaiya (Ọlọhun), a o gbewọn jinna si i.

وَسَيُجَنَّبُهَا ٱلْأَتْقَى ١٧

**18.** Ẹniti o nfi owó rẹ̀ tọrẹ, lati fi fọ ẹ̀mi rẹ̀ mọ.

ٱلَّذِى يُؤْتِى مَالَهُۥ يَتَزَكَّىٰ ١٨

**19.** Atipe kòsi ẹnikan ti o ni Õre idẹra kan lọdọ rẹ̀ lati fi gba ẹsan.

وَمَا لِأَحَدٍ عِندَهُۥ مِن نِّعْمَةٍ تُجْزَىٰٓ ١٩

**20.** Ayafi lati fi wa ojure Oluwa rẹ̀ ti O ga julọ.

إِلَّا ٱبْتِغَآءَ وَجْهِ رَبِّهِ ٱلْأَعْلَىٰ ٢٠

**21.** Atipe laipẹ yio di ẹniti o nyọnu.

وَلَسَوْفَ يَرْضَىٰ ٢١

## *(93) Suratul - Dhuhã*

سُورَةُ ٱلضُّحَىٰ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aṣakẹ ọrun.*

بِسْمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحْمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Mo fi imọlẹ̀ iyalẹta (Dhùhã) bura.

وَٱلضُّحَىٰ ١

**2.** Ati òru nigbati o ba bolẹ̀ biribiri.

وَٱلَّيْلِ إِذَا سَجَىٰ ٢

**3.** Oluwa rẹ kò fi ọ silẹ, kò si binu si ẹ.

مَا وَدَّعَكَ رَبُّكَ وَمَا قَلَىٰ ٣

**4.** Atipe dajudaju igbẹhin (ọrun) yio dara fun ọ ju akọkọ (aye) lọ.

وَلَلْءَاخِرَةُ خَيْرٌ لَّكَ مِنَ ٱلْأُولَىٰ ٤

**5.** Atipe laipẹ Oluwa rẹ yio fun ọ ni ohun ti yio dun mọ ọ ninu.

وَلَسَوْفَ يُعْطِيكَ رَبُّكَ فَتَرْضَىٰ ٥